# IWE SI OLOTU

## Awọn Na Nfẹ Ẹkunwo Owo-Oṣu

Ẹ dakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe ayin to njade lojojumọ lati ba awọn asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ sọrọ nitoripe awọn ti gbagbe awa ti a nṣiṣẹ labẹ enia Dudu, ko si ẹkunwo fun wa rara awa ni o si nse Iṣẹ to pọ julọ.

Mo bẹ ẹnyin asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ bi Michael Imobu ati Adebọla pe, ki awọn maṣe gbagbe wa awọn enia Dudu ko nfun wa ni aye Isimi lehin ti aba ti ṣe odun kantan.

O wa oṣu wa ko ole rara, ko si igbega rara, eyiti o tilẹ buru nibẹ julọ ni pe, a ki gba owo oṣu wa lasiko, awọn ẹlomiran ninu enia Dudu ko nsan wo titi di bi ọjọ kan san si ekejila osu.

Ni ọjọ kanna ni gbogbo wa ti nra ọja, ti a ti nra aṣọ, bi a ba ya owo ti ada ipari oṣu bi osu ba pari, a ki ri owo san a o wa ma da ọjọ titi ti oju yio fi mọ ti wa

Mo bẹ nyin ẹ ran wa lọwọ bi Ọlọla Morgan ba ti gbe Iwadi rẹ jade ẹ ma gbagbe wa o Olotu mo dupẹ aye ti o gba mi o, ẹkunwo oṣu ko ni rekọja nyin o

Emi ni
Lati Arẹmu
MUSHIN

## A nfẹ Irohin Imọlẹ Ni Akurẹ

Olotu mi yio dun pupọ ki ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyin mẹmọ ti njade lojojumọ lati ba awọn alaṣẹ iwe Irohin Imọlẹ sọrọ nipa iwe Irohin na ti ko nlẹtẹ tẹ wa lọwọ. awọn ti o ba lọ si Ibadan Oshogbo ati bẹẹbẹ lọ ni on mọ ni wọn lọwọ.

Awọn diẹ ti nwọn ba ko wa si Akurẹ logan ni o ntan, ti ọpọlọpọ ko nsi ri iwe na ka rara elo miran yio wahala titi ki ele ba ri iwe irohin Imọlẹ ra gbogbo rẹ pabo ni o nbọ si.

Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le ni asoju kan ni ilu Akurẹ ti yio jẹ ki a mọ ri iwe Irohin Imọlẹ ka lojojumọ

Nitoripe a w a na fẹ mọ ka irohin lojojumọ bi awọn ti nka ede oyinbo ti nka ti wọn na aki fẹ ki awọn kan mọ tumọ iro fun wa mọ

Nibiti aiye de loni yi, ko yẹ ki a mọ ka irohin nkan to ba ti ṣelẹ ni ọjọ mẹjọ-mẹjọ mọ, a nfẹ mọ ka lojojumọ iwe Irohin Imọlẹ ni o sile mọ fun wa ni irohin lojojumọ. Ẹ jọwọ o ẹjẹ ki a mọ ri iwe Irohin Imọle ka o

Emi ni
J Atolagbe
AKURẸ

## Ado Ekiti fẹ Ile wosan nla

Olotu inu mi yio dun bi ẹba le gba mi ni aye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Oruo Naijiria jati ṣe iranlọwọ yi fun wa iranlọwọ ti anfẹ lati ẹdọ Ijọba ipinlẹ iwọ orun ni Ile iwosan ti yio tobi Iju eyiti owa ni ilu wa Ado Ekiti ọ ẹpọlọpọ awọn enia to nku sinu ile iwosan to wa tẹlẹ nipe ki iṣẹ gbogbo ohun ti wa ni ile iwosan nla miran lo wa ni ile iwosan ti ilu Ado-Ekiti ati pe ki a si tun dupẹ lọwọ awọn ijọ Aguda to fi idi ile iwosan lelẹ si ilu Ado-Ekiti inu wa yio dun bi ijọba Ipinlẹ ba le ṣe iranlọwọ fun wa lati le kọ ile iwosan titun miran lati le din ọmọ ọpọlọpọ iku awọn ọmọde ni ilu na na. Inu wa yio si dun bi Olotu ijọba i, inlẹ na ba le ṣe iranlọwọ eyi fun wa. Mo dupẹ o Olotu ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ o Amin

Emi ni
Kọlawọle Olupo
EKO

## Oju Ọna Yi Ko Dara

Ẹdakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti nkọwa ni ọgbọn ati oye ti o si tun ntumọ Yoruba yekeyeke fun wa lati ba Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun sọrọ lori oju ọna lati Ibadan lọ si Iwo

Bi enia ba rin oju ọna na ko ni mọ wipe ọda wa loju ọna na, nitoripe niṣe ni ọkọ yio ma jasi koto jasi gegele to jẹ wipe bi oluwarẹ ba ti sọ ninu mọto larin ọjọ mẹta ara yio ma ro enia.

Mo bẹ gbogbo ẹyin Ijọba Ibilẹ Ibadan ati Iwo pe, ki ẹjẹ ki a ran awọn enia to ngbe agbegbe ilu mejeeji lọwọ nipa pe ki a tun oju ọna na ṣe ki ojo ki o to de.

Oju ọna na ti bajẹ rekọja nitorina oju ọna yi ti ba jẹ kọja eyiti ale fi silẹ di igba miran, ẹba wa tete moju to ọna na o. Awọn enia to wa ni agbegbe na, ọgan ni nwọn mọ san owo ori wọn si apo Ijọba.

Mo dupẹ lọwọ rẹ Olotu fun aye ti ẹ gba mi, ọkọ ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o.

Emi ni,
Alli,
Iwo.

## Ẹma Polowo Ọja Yin Sinu Iwe-Irohin Imọlẹ lojojumọ


BERE OJULOWO EGBOI AWỌN FARANSE TI NWỌN NPE NI - Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHELET**

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu ẸJẸ ARA' bi Mọna-mọna,

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si ni kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyọn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pelu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mo tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fuu ẹlomina pẹlu.

Bere Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria. Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMISTS'
14, WAKEMAN STREET' YABA.



## IWẸ ITUMỌ ALA

Josẹfu Alala ti ẹ ti nka ninu iwe Irohin Yoruba i jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ al rẹ wo.
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ bi o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun,

Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N/ Shittu Street
Ibadan
tabi
1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ,
Via Suru—Lere,
Yaba

# Benson Yẹra Fun Ipade Ẹgbẹ Alakukọ

EKO:— alakoso eto irohin ijọba apapọ Ọgbẹni T. O S. Benson ti o jẹ ẹnikan ninu ọrọ kan ti o jẹ mọ ede aiyede to bẹ silẹ ninu ẹgbẹ Alakukọ larin bi ọsẹ melo kan sẹhin kọ ipade ti awọn alagba ti awọn ọmọ ẹgbẹ ti Ipinlẹ Iwọ Orun pe Ọgbẹni Benson silẹ lailọ rara. Ninu ọrọ ti awọn a ba ẹgbẹ na fẹ ṣe iwadi rẹ ni ọrọ kan ti o jẹmọ ti ẹgbẹ Dẹmọ fi nwọn sẹsẹ da silẹ laipẹ yi ti nwọn si nsọ pe Ọgbẹni Benson si ni ọmọ ninu ẹgbẹ na

Ọgbẹni Benson fi ye awọn onirohin pe ohun to fa ti on ko fi lọ si ipade na ni pe on ni ọpọlọpọ nkan lati ṣe ati pe nwọn ko sọ fun on pe ọjọ kẹfa osu yi ni nwọn fẹ ṣe ipade na.

Ninu awọn to wa si ipade na ni Oloye Jas O. Sofidija ati Oloye Ọdunlami awọn meji si jẹ ninu awọn alagba ọmọ ẹgbẹ N.C.N.C. ti Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye Olu Akinfosilẹ alaga oludari iṣẹ ẹgbẹ N. C. N. C. ti Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye Harold Shodipọ Oloye Richard Akinyẹmi, ati Oloye Adeoye Adisa. Nwọn si ṣe ipade na fun igba diẹ ki nwọn to sọ pe nwọn yio sun ipade na siwaju diẹ titori Ọgbẹni Benson ti ko wa sibi ipade na.

Nwọn si ti sun ipade na si ọsẹ to nbọ nigbati awọn olori ẹgbẹ na si ro pe Ọgbẹni Benson yio si wa si ipade na.

Ọgbẹni Benson si tun fi ye onirohin pe on yio wa si ipade ti nwọn ba si pe ipade na si ọna to tọ to si yẹ ati nigbati o ba si ara

## * YẸ IRAWỌ RẸ WO *

AQUARIUS (Jan 22—Feb20) Iṣẹ ti o kọ ti o nṣe lọwọ le bajẹ loni maṣe sọ wipe, nitorina, iwọ ko ṣe mọ, ire ojiji le yọ si ọ ni aṣalẹ oni, ṣọ owo ọwọ rẹ na.

PISCES (Feb 21—Mar 20) Gbogbo iṣẹ ti o ba dawọle loni ire ni yio jasi, ṣọra, ki o maṣe padanu, bi iwọ ba ṣe inure maṣe jẹki o ju agbara rẹ lọ.

ARIES (Mar 21—April 20) Ija kan mbọ ayafi ki o ṣe suru ki o maṣe ja ki alafia rẹ maṣe bajẹ. Lalẹ oni ewu yio lọ lori rẹ iwọ yio bọ kuro ninu ijangbọn

TAURUS (April 21—May 20) Ọrẹ gbogbo ti o ni. alaigbọnran ni wọn ki gbọ, ki gba ni wọn, nipa bẹ ibi, kan ti ẹ fẹ lọ ko ni ṣe mọ. Ẹrin ni ki o ma rin, fi ori ti i, ki o si m ṣe jẹjẹ n'gbana eke loju yio ti

GEMINI (May 21-June 21) K o si orire fun ọ loni, sa fi ara balẹ wo, ki o si tun ro ọrọ na latẹhin wa, lo ọgbọn ri lati yara fun awọn nkan miran.

CANCER (June 22-July 23) Tun ọrọ rẹ ro daradara ki o to fi iṣẹ, nitori kekere ni iwọ yio pe, yio si di nla, bi o ba di irọlẹ, ire kan le yọ si ọ lọna iyanu

LEO (Jut 24-Aug. 22) Ire yio jade loni bi o bi lọ bẹ awọn ọrẹ wo, ṣe pẹlẹpẹlẹ, maṣe wa ẹnikẹni na ija, ṣọra ki o ma ba padanu owo loni.

VIRGO (Aug. 23-Sept. 23) Gbogbo ọna ibi iṣẹ rẹ yio lere loni, masi ṣe ba adehun awọn ti o yi ọ ka jẹ, fun gbogbo nkan ti o ba fẹ ṣe, fi ọgbọn sinu ki o fi wọn pamọ di gba miran.

LIBRA (Sept. 24-Oct. 23) Irẹpọ ko ni ba ode pade loni Maṣe ba ẹnikan sọrọ lile pataki julọ maṣe binu si ọrẹ rẹ Obinrin mura lati ma lọ siwaju, ifasẹhin ni ko sunwọn.

SCOPIO (Oct' 24-Nov. 22) Ire mbẹ fun ọ loni, bi o ba ri ẹniti yio ṣe iranlọwọ fun ọ. Maṣe ba Obinrin kan ta lẹnu iṣẹ ki ara rẹ ma ba gbẹkan ki o ma ba di ọran si ọ lẹrun lẹnu iṣẹ,

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Mura ki o si duro gbọingbọin lẹnu iṣẹ rẹ, iwọ yio ri irohin buruku kan gbo' saragiri maṣe sori kodo nitori rẹ

CAPRICORN (Dec 23-Jan 21) Bi ẹrọ inawo kan ba fi ara bale fun ọ ohun to dara ni ko o nawo ẹyọ na, maṣe binu masi ṣe ja iwọ yio jẹ anfani rẹpẹtẹ ninu rẹ

BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹanṣoṣo ki o ri iyatọ*

**Congreves Female Remedy**

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi tituo fun gbogbo awọn Obinrin hoba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, Ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi aiperinyọ esia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Oloye Johnson Ṣi Ile Ẹkọ Awọn Obinrin

IDI ARABA:— Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejiia oṣu yi ni Alakoso eto iṣẹ ati idarayi Oloye J. M. Johnson si ile ẹkọ tuntun kan fun awọn Obinrin eyi ti nwọn si fi £150,000 kọ si Surulere.

Ninu ọrọ rẹ nibi ẹyẹ iṣi le ẹkọ tuntun na Oloye Johnson rọ gbogbo awọn enia lati ni ifi ọwọ ṣowọpọ fun awọn ọmọde kakiri orilẹ ede Naijiria fun isowọpọ nipa ti owo ati lọnakọna

Oloye Johnson si sọ pe gẹgẹbi Ijọba sẹ ti mọ ati pe nwọn yio gbiyanju gidigidi lati ran awọn ọmọde lọwọ.

Oloye Johnson si tọka si gẹgẹbi nwọn ṣe nkọ awọn ọmọde wọ ilu Eko nipa ọna airi iṣẹ ṣe awọn ọmọ wọnyi nwọn si nbọ si ọwọ awọn enia orişirişi ti ko si ni fun wọn ni nkan ti nwọn si nfẹ ti nwọn yio fi ma ko ẹgbẹkegbẹ.

Oloye Johnson si rọ gbogbo awọn enia jakejado la ti ni iranlọwọ fun awọn ọmọde'binrin wọnyi.

Siwaju si Olotu Alakoso ti ndari eto iṣẹ itọju idaraya ati eto iṣẹ Iyaafin W. A. Mc Ewen si sọ ninu ọrọ rẹ pe Oloye Johnson si jẹ ẹnikan to fẹran awọn ọmọde. Iyaafin Mc Ewen si tun sọ pe Oloye Johnson si ma ni isowọpọ lati le ri pẹ iṣẹ to ti ba ti eto idagbasoke ati itọju ti awon ọmọde lọ ati pe o si ni isowọpọ pẹlu nwọn. Iyaafin Mc Ewen si sọ pe on si ni ero pe Oloye Johnson yio ma ba ọrọ rẹ lọ gẹgẹbi idagbasoke yio ṣe wa fun awọn ọdọ ilẹ yi.

Ile ẹkọ na ni ile ẹkọ fun awọn obinrin kan fun awọn ọmọ ti ko ni enia ati ile kan fun lati ma ṣe iṣẹ to jẹmọ ti eto ilera ati idagba soke awọn ọdọ ile meji tun wa fun awọn ọga ile iṣẹ awọn ti nṣe akoso ile iṣẹ na ati awọn ile mejila fun awọn ọga kekere ti ndari ile iṣẹ eto idagbasoke ati ilera.

Ọpọlọpọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin lowa jakejado ilẹ Naijiria.

Oloye Johnson si ṣe abẹwo awọn ọmọ obinrin to wa lẹnu iṣẹ ni ile ẹkọ titun na o si ba wọn ṣere.

---

## AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ jakejado Ilẹ Naijiria pe ỌTẸLẸMUYẸ ti ajo de nişişiyi. Ọrọ rẹ yio si ma a jade ninu IROHIN IMỌLẸ deede nişişiyi nitorina ki awọn onkawe wa mura silẹ lati ma a ka igilangọ ọrọ ỌTẸLẸMUYẸ ti yio ma jade ninu Iwe wa na

OLOTU

---

# Itan Ajiran Ilu Awọn Oku

Lati Oju Ewe Keji

abirun lori-Ẹyin ọmọ enia lo le mi kuro ni ile aiye, ẹnyin abirun lo sọ mi di ẹni ti o ngbe isalẹ ami, Aro ni ni mo ti nrẹ jẹjẹ ri, ẹnyin lẹ sọ mi di ẹniti o nba ẹja tọwọ pọ laiṣe ẹja. Ha! ẹnyin ọmọ enia ẹ tun wa mi ibugbe mi, ẹnyin ti ẹ wa ba mi ṣe ajọyọ, ẹ tẹ ti ki ẹ gbọ

Aiye to-to-to funun, aiye akemara Ọmọ araiye lo nsọ igba di ọgbun awọn enia ti mo npe ni aiye lo duro niwaju mi yi, Inu wọn kun fun oro, akeke, ọtẹ ati jamba.

Mo ti fi ọjọ ibi mi bura pe, emi pẹlu Ọmọ enia ko ni ṣe pọ mọ lailai, enia lọ tọ̃ọ ijimere bọ epo, enia ni ọsin ke wọgbo kiniun ọbọ ẹranko ko le gbagbe enia lailai, aiye kẹ so, aiye ko suuwọn, aiye to-to-to fun nu njẹ o ha yẹ ki wọn lọ laipẹ wọn bi nyin ara ? Gbogbo awọn ti o wa nibẹ ke pe, pa wọn pa wọn. pipa ni wọn

Nibiyi ni ngo da ọrọ mi duro loni, ṣugbọn ki e ma ṣe gbagbe pe, ngo un ma ba itan na lọ ni ọla.

O darọ o.

---

# wọ Ha Nlọ Si ẹkka Ni Ọdun To Nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ŞINA TABI NA OWO INA KUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa ọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin'

WAS SALM"

AKIYESI: Gbogbo Musulumi Ododo lo ye ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA.

Iye Owo 5/6 £3 fun dọsini
MANAGER
N2/99 SHITTI STREET,
Ibadan

---

# Ẹ ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

---

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYI NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi se şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradarawọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun lọ si ded'adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Sreet, Yaba

